EFF'S SURVEILLANCE SELF-DEFENSE

# YÍYAN IRINṢẸ́Ẹ̀ RẸ

*https://ssd.eff.org/en/about-surveillance-self-defense*

LOCALIZATION LAB

## Yíyan Irinṣẹ́ẹ̀ Rẹ

Ìtúnwò Ìkẹyìn:
5-8-2018

Pẹ̀lú ọ̀pọ̀ ilé-iṣẹ́ àti ibùdó-ìtàkùn tí ó ní irinṣẹ́ fún mímú ààbò ẹ̀rọ ayélujára rọrùn, báwo ni ó ṣe yan irinṣẹ́ tó dára fún ọ?

A kọ́ ní òǹkà irinṣẹ́ tó jọjú ń gbèsè tí ó lè dá ààbò bò ọ́ (bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé o lè rí àwọn àṣàyàn tó wọ́pọ̀ nínú ìtọ́nà irinṣẹ́ wa). Ṣùgbọ́n bí o bá ní iyè rere ohun tí ò ń gbìdánwò láti fi ààbò bò, àti ẹni tí ò ń gbìdánwò ṣe ìdáààbòbò fún, ìtọ̀nà yìí lè ràn ọ́ lọ́wọ́ láti yan irinṣẹ́ tí a yà sọ́tọ̀ nípa lílo àwọn ìtọ́nà kan.

Rántí, ààbò kì í ṣe nípa ti irinṣẹ́ tí o lò tàbí iṣẹ́-àìrídìmú tí o gbà sílẹ̀. Ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú níní òye ìdẹ́rùbà tí ò ń kojú àti bí o ṣe lè lòdì sí ìdẹ́rùbà wọ̀nyẹn. Yẹ ṣíṣe ìdíyelé ewuù rẹ wò fún àlàyé lẹ́kùnúnrẹ́rẹ́.

## Ìgbésẹ̀ ni ààbò, kì í ṣe ohun tí a rà

Ohun àkọ́kọ́ tí ó yẹ k'á rántí kí a tó pààrọ̀ iṣẹ́-àìrídìmú tí ò ń lò tàbí ríra irinṣẹ́ tuntun ni pé kò sí irinṣẹ́ tàbí iṣẹ́-àìrídìmú tí yóò fún ọ láàbò pátápátá. Nítorí bẹ́ẹ̀, ó ṣe pàtàkì láti wòye nípa ìwà ààbò ẹ̀rọ ayélujára porongodo. Fún àpẹẹrẹ, bí o bá fẹ́ ẹ́ lo irinṣẹ́ ààbò lórí ẹ̀rọ-alágbèékáà rẹ, síbẹ̀ máà fi ọ̀rọ̀-ìfiwọlé sórí ẹ̀rọ-ayárabíàṣáà rẹ, irinṣẹ́ orí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ lè máà ràn ọ́ lọ́wọ́ tó bẹ́ẹ̀. Bí ẹnì kan bá fẹ́ ẹ́ wá ìwífún nípa ìrẹ, ó máa yan ọ̀nà tó rọrùn jù láti rí ìwífún náà gbà dípòo ọ̀nà líle.

Lọ́nà kejì, ó ṣe kókó láti dá ààbò bo onírúurú ẹ̀tàn, tàbí àdojúkọni, nítorí náà o ní láti f'ọkàn sí irú ènìyàn tí o lè fẹ́ jí ìwífún-ùn rẹ, ohun tí wọ́n fẹ́ fi ṣe, àti bí wọ́n ṣe lè rí i. Bí olúborí ìdẹ́rùbà rẹ bá jẹ́ ìbojúwò ojúkorojú láti ọ̀dọ̀ aṣèwádìí ìkọ̀kọ̀ kan tí ò rí àyè láti lo irinṣẹ́ ìbojúwò ẹ̀rọ-ayélujára, o kò nílò láti ra ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ owó iyebíye tí ó ń sọ ìwífún di odù fún ààbò tí ó ní "NSA-proof"
Ẹ̀wẹ̀wẹ̀, bí o bá kọjú ìjọba tó máa ń fi èèyàn sátìmọ́lé nítorí o lo irinṣẹ́ ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò, ó fọgbọ́nyọ bí a lo ọ̀nà tí ó ní akitiyan tó bẹ́ẹ̀ - bíi títo àkójọpọ̀ odù tí ò ní ewu, àtòélẹ̀ tí yóò gbé iṣẹ́-ìjẹ́ - ju kí a fi ẹ̀rí tí ó ní éwu wípé a lo iṣẹ́-àìrídìmú ayí-ìwífún-padà-sí-odù fún ààbò lórí ẹ̀rọ-ayárabíàṣá àgbélétan. Gbígbé àkójọpọ̀ ìdojúkọ tí o  lọ́kàn láti fi ààbò bò ni à ń pè ní àwòṣe ìdẹ́rùbà.

Pẹ̀lú gbogbo ìwọ̀nyí, ìwọ̀nyí ni ìbéèrè tí o lè ṣe kí o tó gba ẹ̀dà irinṣẹ́ sílẹ̀, rà á, tàbí lò ó.

## Báwo ni mímọ́ gaara rẹ̀ ti rí?

Oníwàdìí ààbò ní ìgbàgbọ́ wípé ìṣísílẹ̀ àti mímọ́ gaara ni ó ń ṣokùnfa irinṣẹ́ ààbò lọ́pọ̀ yanturu. Ọ̀pọ̀ nínú iṣẹ́-àìrídìmú tí àwọn òǹlò ẹ̀rọ ayárabíàṣá ń lò tí wọ́n sì fi òǹtẹ̀ lù ni irinṣẹ́ fún lílò. Èyí túmọ̀ sí wípé odù tí ó fi ń ṣiṣẹ́ ń wà ní gbangba fún ẹlòmíràn láti yẹ̀wò, túnṣe, àti ṣe àtúnpín. Nípa mímọ́-gaara irinṣẹ́ẹ wọn, oníṣọ̀nà irinṣẹ́ wọ̀nyí fìwé pe ẹlòmíràn láti yẹ ààbò wọn wò bóyá ó kú díẹ̀ káàtó àti láti ṣe ìmúgbòrò irinṣẹ́ náà.

Iṣẹ́-àìrídìmú ìṣísílẹ̀ ń fún ni láǹfààní ààbò tó péye, ṣùgbọ́n èyí kò dájú. Dídára iṣẹ́-àìrídìmú ìṣísílẹ̀ wà lọ́wọ́ àwọn onímọ̀ tó ń yẹ odù iṣẹ́-àìrídìmú ìṣísílẹ̀ wò, tí, fún iṣẹ́ kékeré (àti èyí tó gbajúmọ̀, tó díjú), lè nìra láti ṣe.

Bí o bá fẹ́ yan irinṣẹ́, wò ó bóyá odùu rẹ̀ wà láròọ́wọ́tó àti bóyá ó ní ajẹ́rìí ààbò àdáni láti fẹsẹ̀ agbára ààbòo rẹ̀ múlẹ̀. Ó kéré jù, ó yẹ kí iṣẹ́-àìrídìmú tàbí iṣẹ́-àrídìmú ó ní àlàyé lẹ́kùnúnrẹ́rẹ́ nípa ìṣiṣẹ́ẹ rẹ̀ fún àtúnyẹ̀wò àwọn onímọ̀.

## Àtẹ̀jíṣẹ́

Àtẹ̀jíṣẹ́ tí a mọ̀ bí ẹní m'owó (SMS) ò lo ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò òpin-dé-òpin. Bí o bá fẹ́ fi iṣẹ́-ìjẹ́ tí a ti yí dátà rẹ̀ padà sí odùu ààbò ránṣẹ́ lórí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ rẹ, o ò ṣe lo iṣẹ́-àìrídìmú ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò fún iṣẹ́-ìjẹ́ oníwàràǹṣesà dípò àtẹ̀jíṣẹ́.

Díẹ̀ nínú àwọn iṣẹ́-ìjẹ́ oníwàràǹṣesà tí a ti yí dátà rẹ̀ padà sí odùu ààbò ìfẹ́nukò ti wọn. Wàyí, ẹ wò ó báyìí, àwọn òǹlòo Signal lórí Android àti iOS lè sọ̀rọ̀ bótibòti pẹ̀lú ààbò lóríi gbàgede wọ̀nyí.
Áàpù tí máa ń yí odù ìtàkùrọ̀sọ padà fún ààbò pẹ̀lú OTR lórí èyíkéyìí ìṣàsopọ̀ tó ń lo XMPP ni ChatSecure, tí ó túmọ̀ sí wípé ó lè ṣ'àṣàyànan nínú oríṣiríṣi iṣẹ́-ìjẹ́ àdádúró tí ó hùn ọ́ nínú àìmọye tó wà.

## Iṣẹ́-ìjẹ́ Oníwàràǹṣesà

Àtẹ̀jíṣẹ́ tí a mọ̀ bí ẹní m'owó (SMS) ò lo ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò òpin-dé-òpin. Bí o bá fẹ́ fi iṣẹ́-ìjẹ́ tí a ti yí dátà rẹ̀ padà sí odùu ààbò ránṣẹ́ lórí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ rẹ, o ò ṣe lo iṣẹ́-àìrídìmú ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò fún iṣẹ́-ìjẹ́ oníwàràǹṣesà dípò àtẹ̀jíṣẹ́.

Díẹ̀ nínú àwọn iṣẹ́-ìjẹ́ oníwàràǹṣesà tí a ti yí dátà rẹ̀ padà sí odùu ààbò ìfẹ́nukò ti wọn. Wàyí, ẹ wò ó báyìí, àwọn òǹlòo Signal lórí Android àti iOS lè sọ̀rọ̀ bótibòti pẹ̀lú ààbò lóríi gbàgede wọ̀nyí.
Áàpù tí máa ń yí odù ìtàkùrọ̀sọ padà fún ààbò pẹ̀lú OTR lórí èyíkéyìí ìṣàsopọ̀ tó ń lo XMPP ni ChatSecure, tí ó túmọ̀ sí wípé ó lè ṣ'àṣàyànan nínú oríṣiríṣi iṣẹ́-ìjẹ́ àdádúró tí ó hùn ọ́ nínú àìmọye tó wà.

Ìfẹ́nukò  ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò òpin-dé-òpin fún ìtàkùrọ̀sọ alátẹ̀jíṣẹ́ ojú-ẹsẹ̀ tó ṣe í lò lórí onírúurú iṣẹ́ ni Àìsí-lákọsílẹ̀ (OTR).

Àwọn irinṣẹ́ tó ní OTR nínú pẹ̀lú iṣẹ́-ìjẹ́ oníwàràǹṣesà ni :

- Pidgin (fún Windows tàbí Linux)
- Adium (fún OSX)
- ChatSecure (fún iPhone and Android)
- Jitsi (Linux,
- Windows, Mac OS)

## Ímeèlì

- Pidgin (fún Windows tàbí Linux)
- Adium (fún OSX)
- ChatSecure (fún iPhone and Android)
- Jitsi (Linux,
- Windows, Mac OS)

Ọ̀pọ̀ apèsè ímeèlì fún ọ láàyè láti yẹ ímeèlìi wò lórí ìtàkùn aṣàwáríkiri, gẹ́gẹ́ bíi Firefox tàbí Chrome. Nínú apèsè wọ̀nyí, ìtìlẹ́yìn wà fún HTTPS, tàbí ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò ìpele-ìṣíkúrò. Ó lè mọ̀ bí apèsè ímeèlìi rẹ bá pèsè ìtìlẹ́yìn HTTPS fún ọ bí o bá wọlé sínú ìtàkùn-ímeèlì rẹ àti URL orí òkè aṣàwáríkirìi rẹ tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú lẹ́tà HTTPS nípò HTTP (fún àpẹẹrẹ: https://mail.google.com)

Bí apèsè ímeèlì rẹ bá ní ìtìlẹ́yìn fún HTTPS, ṣùgbọ́n tí kò ṣe bẹ́ẹ̀, gbìyànjú kí o pààrọ̀ HTTP pẹ̀lú HTTPS nínú URL kí o sì tún ojúùwé náà tẹ̀. Bí o bá fẹ́ ìdánilójú wípé HTTPS lo máa ń lò ní gbogbo ìgbà lórí ibùdó tí ó bá wà, gba ẹ̀dà àfilé HTTPS Níbigbogbo sílẹ̀ fún lílò lóríi asàwáríkiri Firefox tàbí Chrome.

Apèsè imeèlì ìtàkùn àgbáyé tó máa ń lo ààtò-àbáwá HTTPS ni :

- Gmail
- Riseup
- Yahoo

Apèsè ìtàkùn-ímeèlì mìíràn fún ọ láàyè láti yan HTTPS gẹ́gẹ́ bí àbáwá tí o lè yàn nínú ààtò rẹ. Èyí tó gbajúmọ̀ jù lọ ni Hotmail t'ó ṣì ń ṣe bẹ́ẹ̀ dòní.

Kí ni ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò ìpele-ìṣíkúrò ń ṣe àti ìdí tí o fi lè nílòo rẹ fún?
HTTPS, tí a tún mọ̀ sí SSL tàbí TLS, máa ń yí dátà ìtàkùrọ̀sọ̀ rẹ padà-sí-odù-ààbò kí ẹlòmíràn ó máà bá a rí i kà lóríi ìṣàsopọ̀ rẹ. Èyí lè kan àwọn tí ẹ jọ ń lo WiFi kan náà ní pápákọ̀ òfuurufú tàbí ní ilé ìjẹun, àwọn ẹlòmíràn ní ibiiṣẹ́ tàbí ilé ìwé, alákòóso ilé-iṣẹ́ apèsèe (ISP) rẹ, olè apanilára, ìjọba, tàbí àjọ agbófinró. Ìtàkùrọ̀sọ tí o fi ránṣẹ́ lóríi ìtàkùn aṣàwáríkirìi rẹ, tití kan ìtàkùn ojú-ìwé tí o lọ àti ohuninú ímeèlì rẹ, ìwé-ìrántí ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé àti iṣẹ́-ìjẹ́, lílo HTTP dípò HTTPS f'ààyè gba adojúkọni láti dí ìtàkùrọ̀sọ̀ rẹ lọ́wọ́ àti kà á.

HTTPS ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò ìtàkùn aṣàwáríkirìì rẹ tí a f'ọwọ́ sí fún ènìyàn gbogbo. Ó dàbíi síso okùn ààbò ìjókòó bí o bá ń wa ọkọ̀.

Àmọ́ ó ní àwọn ohun tí HTTPS kì í ṣe. Bí o bá fi ímeèlì ránṣẹ́ lórí HTTPS, apèsèe ímeèlì rẹ yóò ṣì rí ẹ̀dà ìtàkùrọ̀sọ̀ọ̀ rẹ tí data ò yí odù rẹ̀ padà fún ààbò. Ìjọba àti agbófinró lè rí dátà rẹ pẹ̀lú ìwé àṣẹ. Ní ìlú America, ọ̀pọ̀ apèsèe ímeèlì ló ní ìlànà àti àkọsílẹ̀ pé wọn yóò wí fún ọ bí àwọn ìjọba bá l'áwọ̀n-ọ̀n fẹ́ ẹ́ rí dátà rẹ gẹ́gẹ́ bí òǹlò, níwọ̀n ìgbà t'áṣẹ bá f'ààyè gbà wọ́n, ṣùgbọ́n ìlànà yìí kì í ṣe tipá, àti pé lọ́pọ̀ ìgbà ni òfin kò fún apèsè láyé láti sọ fún òǹlò wípé ìjọba béèrè fún dátà rẹ̀. Apèsèe ímeèlì, gẹ́gẹ́ bíi Google, Yahoo, àti Microsoft, tẹ àtẹ̀jádé ìròyìn mímọ́ gaara tó ń s'àlàyé iye ìbéèrè fún dátà òǹlò tí wọ́n ti gbà, ìlú t'ó béèrè fún un, àti iye ìgbà tí ilé-iṣẹ́ náà ti fi dátà ṣọwọ́ sí ìjọba.

Bí àwòṣe ìdẹ́rùbà rẹ bá ní ìjọba tàbí agbófinró nínú, tàbí o ní ìdí mìíràn fún àìfààyègba apèsèe ímeèlì láti fi ohuninúu ímeèlì rẹ ránṣẹ́ sí ẹnìkẹ́ta, o lè fẹ́ ẹ́ máa lo ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò òpin-dé-òpin fún ìtàkùrọ̀sọ̀ọ̀ ímeèlì rẹ.

PGP (tàbí ibi-ìkọ̀kọ̀ tó dára jù) ni ìyódùpadàfáàbò òpin-dé-òpin tí ó dára jù fún ímeèlì rẹ. Bí o bá lò ó lọ́nà tó yẹ, ó máa dá ààbò bo ìtàkùrọ̀sọ̀ọ̀ rẹ. Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí bí o ṣe lè fi àti lo ìyódùpadàfâbò PGP fún ímeèlì rẹ, wo:

- Bí a ṣe n: lo PGP fún Mac OS X
- Bí a ṣe n: lo PGP fún Windows
- Bí a ṣe n: lo PGP fún Linux

## Ímeèlì

Ìyódùpadàfâbò òpin-dé-òpin ń dáàbò bo ohuninú ìtàkùrọ̀sọ rẹ ni, kì í dáàbò bo ìtàkùrọ̀sọ tìkararẹ̀. Kì í dáàbò bo mẹ́tádatà - tí í ṣ'àpèjúwe ohun gbogbo nípa dátà, tí ó fi kan ilà àkórí ímeèlì rẹ, tàbí ẹni tí ó ń tàkùrọ̀sọ pẹ̀lú àti ìgbà tí o tàkùrọ̀sọ.

Mẹ́tádatà yìí lè pèsèe gbogbo àṣìírí nípaà rẹ nígbà tí ohuninúu ìtàkùrọ̀sọ rẹ ń bẹ níkọ̀kọ̀.

Mẹ́tádatà nípa ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ lè kó ohun ìkọ̀kọ̀ àti àṣìírí̀ rẹ gbogbo síta. Fún àpẹẹrẹ:

- Wọ́n mọ̀ wípé o pe ilé iṣẹ́ ìbálòpọ̀ ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ọ̀ láago 2:24 ààrọ̀ àti pé o sọ̀rọ̀ fún ìṣẹ́jú 18, ṣùgbọ́n wọn kò mọ kókó ohun tí o sọ̀rọ̀ nípa.
- Wọ́n mọ̀ wípé o pe ilà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ọ̀ pàjáwìrì adíparaẹnilọ́wọ́ láti orí afárá Golden Gate, ṣùgbọ́n kókó ọ̀rọ̀ jẹ́ ìpamọ́.
- Wọ́n mọ̀ wípé o bá ilé iṣẹ́ aṣàyẹ̀wò kòkòrò HIV sọ̀rọ̀, àti oníṣègùn-ùn rẹ, àti ilé-iṣẹ́ adójútòfò ìleraà rẹ ní wákàtí kan náà, ṣùgbọ́n ohun tí ẹ jọ sọ ni wọn kò mọ̀.
- Wọ́n mọ̀ wípé o gba ìpè láti NRA ìjọba ìbílẹ̀ lásìkò ìpolongo ìlòdìsí òfin ìbọn, àti ìpè tí o pe aṣòfin àti aṣojú ilé ìgbìmọ̀ ìjọba lẹ́yìnwá, ṣùgbọ́n ohuninú ìpè náà wà ní ìpamọ́ fún ìjọba.
- Wọ́n mọ̀ wípé o pe onímọ̀-nípa-nǹkan-ọmọbìnrin, o sọ̀rọ̀ fún wákàtí kan àbọ̀, o sì pe àjọ ìfètòsọ́mọbíbí ìbílẹ̀ lọ́jọ́ yẹn náà, ṣùgbọ́n kò s'ẹ́ni t'ó mọ ohun tí ẹ sọ̀rọ̀ nípa

Bí o bá ń pè lórí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká, ìwífún nípa ibi tí o ti ń pè ni mẹ́tádatà. L'ọ́dún 2009, olóṣèlú Green Party, Malte Spitz pe Deutsche Telekom lẹ́jọ́ pẹ̀lú ipá kí wọ́n pèsè dátà ìtàkùrọ̀sọ òun lórí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ fún oṣù mẹ́fà, ó sì gbé e fún ìwé ìròyìn German. Kedere ni àlọ àtàbọ̀ ìgbẹ́sẹ̀ẹ Spitz hàn nínú àwòrán tí wọ́n fún un.

Dídáàábò mẹ́tádatà gba kí o lo irinṣẹ́ mìíràn, gẹ́gẹ́ bíi Tor, bí o ṣe ń lo ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò òpin-dé-òpin

Àpẹẹrẹ kan ni bí Tor àti HTTPS ṣe ń ṣiṣẹ́ pọ̀ láti dáàbò bo ohuninúu ìtàkùrọ̀sọ̀ rẹ àti mẹ́tádatà rẹ lójúran àwọn adojúkọni, o lè fẹ́ yẹ àlàyé yìí wò.

ìtúnwò ìkẹyìn:
1-12-2017

Ó fẹ́ òkétè ohun ààbò alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀?

1. Yíyan Irinṣẹ́ẹ̀ Rẹ
2. Dídáàábò Araà Rẹ lórí Ẹ̀rọ-alátagbà
3. Ìdíyelé Ewuù Rẹ
4. Títàkùrọ̀sọ Pẹ̀lú Ẹlòmíràn
5. Ṣiṣẹ́ Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó L'ágbára
6. Fífi ààbò bo Dátà Rẹ
7. Kí ni ìyódùpadàfáàbò?